Ọlọhun a gba ilẹ mu, yoo si tun ka sanmọ pẹlu ọwọ ọtun Rẹ, lẹyin naa ni Yoo waa sọ pe: Emi ni Ọba, gbogbo ọba (olukapa) ori ilẹ da?

Lati ọdọ Abu Hurayra - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pe: Mo gbọ ti ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - n sọ pe: «Ọlọhun a gba ilẹ mu, yoo si tun ka sanmọ pẹlu ọwọ ọtun Rẹ, lẹyin naa ni Yoo waa sọ pe: Emi ni Ọba, gbogbo ọba (olukapa) ori ilẹ da?».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - fúnni niroo nipa pe dajudaju Ọlọhun ti ọla Rẹ ga Yio gba ilẹ mu ni ijọ igbende ti yio si pa a pọ, ati pe yio ka sanmọ pẹlu ọwọ ọtun Rẹ ti Yio si ka a lori ara wọn tii Yio si pa a rẹ, lẹyin naa ni Yio wa sọ pe: Emi ni Ọba, gbogbo ọba (olukapa) orilẹ da?!

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/65028